# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 837 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 15 — SEPTEMBER 21 1962 KỌBỌ MẸJI (2D)


**ORO BEHIN YO**

# Alakoso Ijoba Ilu Aganyin Di Eleha Apapandodo

ACCRA—Ọrọ bẹhin yọ, Dokita Kwame Nkrumah, Alakoso Ijọba ilu Aganyin, ti nwọn ju ni bọmbu oloro ni aipẹ yi ti di ẹlẹha ọsan gangan ko si le jade kakiri mọ nitori ẹru ti mba a nipa orişirişi iwe ọjọ-iku ti o nri gba lati ọdọ awọn ara ilu rẹ lojojumọ-wipe awọn ni awọn yio pa a.

Onirohin wa sọ fun wa wipe lati bi oşu kan ti nwọn ti ju bọmbu kan si Dokita Nkrumah na pẹlu eyi ti o tun fọnka tagbara tagbara leti ile ti olotu na ngbe ni Christianborg ti gbogbo ilẹ mi titi-titi ti o pa enia mẹtalelọgọta ninu awọn ti wọn pejọ ni ita lati ba Alakoso na kẹdun.

Ni ijẹta ni awọn ogunlọgọ enia kan tun ka ọwọ leri, ti awọn kigbe gba ile ti Alakoso na ngbe lọ, ti nwọn ni dandan awon fẹ ki nwọn yẹgi fun awọn Minisita meji ti Alakoso na rọ loye ti o fi si ajalẹ ni ọgba ẹwọn.

Ilu Aganyan na ko ti toro di bi a ti nkọ irohin yi lọwọ.

## Awon Osise Banki Da Ise Sile

EDẸGBẸTA (500) awọn oşişẹ ile ifowo pamọ kan ti nwọn npe ni United Bank of Africa (ti nwọn ti nje British and French Bank ri) ni nwọn binu da işẹ silẹ l'Eko ni ana nitori akọwe ẹgbẹ wọn ti nwọn da duro.

Onirohin wa ni gbogbo awọn oşişẹ na ti tẹ waya si awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ti nwọn wa lẹhin odi wipe ki awọn na da isẹ silẹ nitori Ọgbẹni Babatunde Animashaun, akọwe ẹgbẹ oşişẹ wọn ti nwọn da duro.

Gbogbo awọn enia ti nwọn lọ si ile ifowo pamọ na lati gba owo ni nwọn ko ri awọn akọwe ti yio da wọn lohun.




# Awo Irawo

## E yi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20)
Maṣe ba wọn lọwọ ninu ija rara lọsẹ yi nitoripe awọn kan a da ija silẹ ti yio fẹ kan ọ; nṣe ni ki o ba wọn pari rẹ. Ti o ba sowo lọsẹ yi wa jere.

PISCES (Feb 21-Mar 20)
Ma ba ẹnikan ninu awọn ọrẹ rẹ jiyan ọrọ rara, ki o si mura lati ṣe iṣẹ karakara.

ARIES (Mar 21-April 20)
Ọsẹ lati fi gbogbo ọrọ sero niyi fun ọ, ṣugbọn nkan ti o ba jẹ pataki ni ki o kọ mu ṣe.

TAURUS (April 21-May 20)
Gbogbo nkan ti o ba fẹ ṣe lọsẹ yi maṣe jẹ ki o jẹ iwọ nikan, jẹ ki ọrẹ rẹ kan ki o ba ẹ lọwọ ninu rẹ ki ẹ si fi tọkan tọkan ṣe e.

GEMINI (May 21-June 21)
Ti o ba fẹ lọ si irin ajo kan ki o jẹ ki o di ọ s ẹ ti mbọ: ma lọ si ibi ti o ba jinna rara.

CANCER (Jun 22-July 23)
O ni lati mu suru pupọ pẹlu awọn ọmọde ti ko to ẹ lọjọ ori, ti iṣẹ ba da iwọ pẹlu wọn pọ. Ki o si ṣọra pẹlu ẹta (3) ko dara rara. Ti o ba ta tẹtẹ wa jẹ.

LEO (July 24-Aug 22)
Gbogbo adehun ti o ba ba enia ṣe ni ko ṣika rẹ larin ọsẹ yi ma ja enia kan tilẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23)
Duro ki o wo iran nitoripe gbogbo ọrọ atijọ ni wa mọ niran ninu ọsẹ yi ki o mọ si fi ṣe iwa hu fun ẹnikan nitoripe ti a ko ba gbagbe ọrọ ana a ko ni ri eni ba ṣere.

LIBRA (Sep 24-Oct 23)
Irawọ rẹ fi irin ajo han si daradara; ti o ba jẹ ọdọmọde wa ba enia ti yio ṣe ọ ni rere pade lẹhin ọla.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22)
Kọ ẹhin si ọrọ jagbajagba, ki o kọju si iṣẹ rẹ daradara.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22)
Gbogbo gbese ti o ba ni lọrun ni ki o san ati awọn ti o ti fe kọ iwe si ki o tete kọ si nwọn.

CAPRISCORN (Dec 23-Jan 21)
Ki o ṣe akiyesi awọn aṣọ tabi golu ti o ba fẹ lo ninu ọsẹ yi, eyi ti o ba pupa diẹ dara.


FIAT





The new versions of the 1100

export saloon    special saloon    station wagon

PRICES

| | EX LAGOS | EX TURIN |
|---|---|---|
| EXPORT SALOON | £680 | £398 |
| SPECIAL SALOON | £750 | £450 |
| STATION WAGON | £800 | £490 |

Quality and price are the driving power of Fiat success -- The fullest range of cars of a single Make: from the small 500 D and 600 D cars to the 1100, the 1300 - 1500, the 1500 S cabriolet and the 1800 B - 2300 -- Fiat: more than ever the car for everybody.

*Available for inspection at*

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (13) • IBADAN • KANO • KADUNA • JOS • PORT HARCOURT • ABA



Advt. NO. 151

**Se o ti lo paro owo atijo owo re**

SI OWO TUNTUN ti ilẹ Nigeria ? O le parọ OWO PEPA kọrẹnsi L'ỌFẸ TITI DI IPARI OṢU SEPTEMBER Ti a wa ninu rẹ yi.

**Ti owo sile ati awon isongbe re di ipari osu**

DECEMBER.

# Kabiyesi Ọba Alake Ademola Keji

## ( Lati owo Omo Abati )

NWỌN ni ko si igi meji obi ninu igbo eyi ti ko ba jọ obi ni njẹ abidun, iyen ni ọrọ Alaiyeluwa Ọba Ademọla Keji, Alake Ẹgba ti yio di ẹni adọrun ọdun ni Ọjọbo (Thursday) ọjọ marun loni; ti o ba si di ijọ mejila a di ọdun mejilelogoji ti o ti gun ori itẹ Ọba Alake ni Abẹokuta.

### Igbalaiye

Ninu gbogbo igbesi aiye awa ọmọ enia, igba mẹta ni o jẹ pataki fun wa; sugbọn ti Alaiyeluwa Ọba wa yi kun fun orisirisi itan ti awọn ọmọkekere yio ri ka lẹhinwa ọla nigbati nwọn ba nka itan awọn ọba nla olokiki ti nwọn ti jẹ nilẹ wa ri ni apa Iwọ Orun Afrika ( West Africa ).

Ni ilu Abẹọkuta ni nwọn bi Alaiyeluwa Ademọla Keji na ni ogunjọ oṣu September ni ọdun 1872; baba rẹ si jẹ Ọba Alake fun awọn Ẹgba niwọn nkan bi ọgọrun ọdun sẹhin.



ỌBA ADEMỌLA KEJI

Gẹgẹbi mo ti gbọ itan na lẹnu baba ti o bi baba mi, Abati Atẹfatẹ'na, Ladapọ ni nwọn sọ Ọba na nigbati nwọn bii, o si jẹ ọmọ ọmọ Tẹnidade, ọmọ-Ọba Jibodu Ọba Alake atijọ; Ọba Ladapọ Ademọla yi si tan mọ OWU.

Nigba ọmọde rẹ, ile-iwe Ake ti nwọn npe ni St. Peter's ni o kọ lọ ni Abẹokuta ki o to wa pari ẹkọ rẹ ni Eko ni ile-iwe ti nwọn npe ni St. Paul's ( Breadfruit ) leti Olowogbowo.

### Ise L'ogun Ise e

Gbara ti ọmọ-ọba yi ti kọ ẹkọ rẹ pari, awọn obi rẹ ko sọ wipe ṣe awọn jẹ Ọba ti o lowo lọwọ, ọmọ awọn le mọ ṣe ọla kiri, ki o si ma rin gbara kiri, ile iṣẹ kikọ ni nwọn ju u si, ti o nsi nkọ iṣẹ awọn ti o ntẹ iwe (printer) labẹ Olotu iwe irohin kan ti nwọn npe ni "Lagos Observer", orukọ Olotu Ọga Ọba na njẹ J. B. Benjamin.

O ṣe iṣẹ na karakara ti o fi de ipo ọga awọn a-tẹ-iwe (head printer) labẹ Ọgbẹni J. P. Jackson, Olotu iwe irohin ọsọsẹ kan ti nwọn npe ni "Lagos Weekly Record" ni nkan bi ọdun mejilelọgọta si igba ti a wa yi. Odun mẹwa gbako ni Alaiyeluwa ṣe gẹgẹbi ọga iṣẹ ninu ile-itẹ iwe na.

Bi o ti kuro lẹnu iṣẹ atẹwe yi tan ni awọn Ijọba Ẹgba yan ni aṣoju (ipo eyiti ẹ npe ni Commissioner nisisiyi) wọn si ilu Eko. Gbogbo igba ti ọmọ ọba yi wa l'Eko awọn ojulumọ enia ni o mba rin, o si ngbe ile kan ni Ita Balogun.

### Ologboni Kemta

Ninu ọdun ti nwọn yan ọmọ ọba Ladapọ si ipo Asoju Ẹgba si Eko ni ijongbọn nla kan bẹ silẹ larin awọn Ologboni adugbo ti nwọn npe ni Kemta pẹlu awọn alakoso Ijọba ilu Ẹgba lori a nṣe idajọ lori awọn ara adugbo.

Tẹlẹ-tẹlẹ ki awọn Alakoso Ijọba Ẹgba to da Kotu igbẹjọ silẹ ni Ake ni iwọn ọgọta ọdun sẹhin, awọn Ologboni ati Parakoyi ilu Ẹgba ni agbara wa lọwọ wọn lati ṣe idajọ lori awọn arufin ilu ati awọn ti nwọn ba kọ oko wọn, ko si si agbara ti nwọn fi nṣe eto ilu ti ko si lọwọ awọn Ologboni yi.

### Ndajo Nile

O jẹ inira fun ọpọlọpọ awọn Ologboni nwọnyi lati fi agbara a ndajọ yi silẹ lẹhinti nwọn da ofin yi silẹ, ti nwọn si ti fi aṣẹ si wipe ẹnikẹni ko gbọdọ da ẹjọ kan labẹ ile rẹ mọ afi awọn onidajọ Kotu Ake, sugbọn Oloye Ologboni Apena Kemta ti o wa nigba na kọ lati maṣe idajọ ninu ile rẹ mọ. O ṣe idajọ kan, awọn Ọlọpa Ẹgba si muu gẹgẹbi arufin.

Bi ko ba si dide ti Ọba Ladapọ Ademọla pẹlu awọn ọmọ Ẹgbẹ ti o nwa ilọsiwaju fun Ijọba ig·a na dide si ọrọ na ko ba di wipe nwọn nta ẹjẹ awọn ara ilu silẹ lori ọrọ na.

### Reluwe

Ṣaju eyi, nigbati Ọba wa yi wa ni ọmọ Ọba ni o ti ba awọn Ẹgba fi ẹgun ẹ·lo ·ẹ·ọ awọn Ijọba Gẹsi l'Eko lori ọrọ ọkọ-ilẹ ti ẹ npe ni Reluwe ti nwọn fẹ mu kọja lori ilẹ awọn Ẹgba.

Nigbati awọn Ẹgba gbọ wipe awọn Ijọba Gẹsi l'Eko (orukọ ti Ijọba Nigeria njẹ nigbana ni yi) fẹ mu ọkọ-ilẹ na gba ori ilẹ wọn, nwọn fi aake kọri, nwọn ni awọn ko fẹ ẹ rara. Ọba Alake yi tun fi ẹsẹ bọ sokoto, o si ba wọn dasi ọrọ na ninu ọdun 1898.

Eleyi jẹki awọn oṣelu Ẹgba fi ọwọ si i ve-adehun na ti Ijọba Gẹsi l'Eko gbe wa siwaju wọn lori ọkọ reluwe yi.

(Ko ti pari)

### Awon Imale Ni Ki Ijoba Ra Ile Si Meka

EKO—Awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti nwọn njẹ Ẹgbẹ Imale Parapọ ilẹ Nigeria ti nwọn ṣe ipade nla kan l'Eko ni aipẹ yi ni nwọn ṣe ipinnu ala kan ninu eyiti nwọn wipe awọn yio kesi awọn olotu Ijọba Apapọ l'Eko wipe ki nwọn jọwọ ki nwọn gba ile kan fun awọn ara

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

---

## AYILUKA NI

**Ibadan lo mo, o ko·mo layipo. Ka oro re loju ewe karun.**

---



# ELETI-OFE

ANJUWỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 468 | "ELETI OFE," LAGOS Phone 23370.

VOL XIV. No. 837. SATURDAY SEPT. 15, - SEPT. 21, 1962


## Awon Alawiye De

LAIṢE iye meji, ẹnyin ọkawe wa a kiyesi wipe lati iwọn nkan bi osu kan wa ni awọn kan ti a le pe oruko w ọ n ni ALAWIYE ti bẹresi ko alaye-ọrọ sinu iwe irohin wa. O bẹrẹ lati ọ d ọ Ọmọ Ọbanta lati I j ẹ b u O d e, Ọ m ọ Lisabi lati Abeokuta ilu Ẹgba so tirẹ, Alheri ọmọ Hausa paapa ṣe Waasi tirẹ; "Erukobodo" ni kilosubu lu on; Ọ m ọ Onikoyi (ọmọ Eko) ni ki nwọn maṣe fọwọ rọ on sẹhin.

### IJA

Ọrọ awọn Alawiye wa na lọtuh losi fa kiki, iyen ni wipe ọrọ pọ nibẹ nitoripe nigbati ọmọ Ọbanta (Ijẹbu) yio pari tirẹ, o ni ni ọ d ọ awọn Ijẹbu ni ọtẹ ati tẹmbẹlẹkun gbe pin si. O ni orin ni saju ọtẹ, awọn ni mọ ọ kọ de opin; awọn ni awọn da orin-ọtẹ "Gedegbe l'Eko wa" silẹ, nitotọ na nwọn si ya ilu Eko na ni gedegbe kuro lọdọ awọn ọmọlẹbi rẹ yoku ni ilẹ Yoruba.

ẸGBA ọmọ LISABI lati Abẹokuta n i awọn korira ọtẹ nitoripe aṣoko ti kọ awọn pe ọtẹ ko nbi ọmọ ni abiye; afi abiku n i bi; rukerudo ati ija-igboro ni o nda silẹ. O ni bi edeaiyede ba si ti de, o yẹ ki a pe Aro inu wa ati Ọdọfin inu wa ki a mọ ona ti a o gbe e gba ki a mo le di ẹni-ẹhin lọla.

"Ẹrukobodo" (n Ife ọmọ Oduduwa) kigbe wipe asiko to! gbogbo ẹnyin Yoruba, ẹ parapọ ki baba-iya ma le jẹ wa. O ni on ko sọ ọrọ o n "lati wa ọmọ kun ọmọ lẹhin Oloye Awolọwọ, bẹni ki iṣe wipe mo nsọ ọ lati ie fi le enia kuro lẹhin Oloye Akintọla."

### Ko' D'ola

ỌMỌ ONIKOYI (Ọmọ Eko) ni n i t i awọn, awọn kiyesi ọdalẹ enia sugbọn ko to, ko si yẹ ki awon sọ ọrọ ibatan awọn na ni ọrọ onigba ni o npe igba re ni aakara ti a fi baa ko ile nitoripe "bi iya-nla ba gbe ni sanle iya kekere a mọ gun ori eni".

ALHERI ọmọ Hausa ni awọn Hausa ko ni ikorira ọkan s'ẹnikan. Boya ẹnyin ọkawe wa ko mọ itumọ oruko Alheri yi -- Oninure ni o njẹ bẹ lede awọn Hausa. Alheri ni ọwọ awa Yoruba ni a fi nfa nkan lile, nitoripe ife lati ni owo lọwọ ọ ti gba ọkan wa papọju. A ko le fẹju fun enia lofẹ.

Tani a le sọ wipe ko sọ ọrọ arikọgbọn ninu a w ọ n Alawiye nwọnyi ? Ṣugbọn nitotọ gẹgẹbi ọrọ Alheri ọmọ Hausa ti o ni bi ọpọlọpọ iya ko ba jẹ awa Yoruba dadadara, a ki mu ogiri si ọrọ ara wa. O ha purọ bi ?

Arun ti o nṣe wa ti kuro ni ti eniti a nfi oru-agbo kan wo san. Amodi olotẹ, ọkanjua enia ati oni-tẹmbẹlẹkun ki i san bọrọ, a fi bi owo ba kan ẹwe. Nitorina a bẹ gbogbo ẹnyin agbalagba ati ẹnyin oṣelu wa, ki ẹjọwọ ki ẹ ba wa tun ilu na ṣe ki o mọ baje lọtẹ ti wa.

## Iwe Si Olotu

## "Erukobodo" Se

Olotu, ẹ ba wa d u p ẹ lọwọ Ọgbẹni wa "Ẹrukobodo" wipe a gbọ nkan ti o wi nipa a w a Yoruba wipe ki a parapọ jẹ aiye o se pupọ. Bi a fẹ, bi a ko si fẹ, nkan ti yio pa wa pọ ti de nisisiyi.

Olotu, boya ẹ le gba mi laye diẹ ki emi na ṣe alaye diẹ fun awọn ọmọ iya mi, Yoruba, nipa gbogbo nkan ti o nlọ ati awọn eyi ti a nri ti a si ngbọ. Emi ko wipe ki ẹnikẹni maṣe ẹgbẹ oṣelu kan o! Ṣugbọn tani ninu awọn oṣelu wa, ko ba ṣe ni Ipinlẹ I w ọ Orun, Ipinlẹ Ariwa tabi ni Ipinlẹ Ila Orun ti nwọn le sọ wipe ara awọn mọ?

Ipakọ onipakọ ni a nri, ẹni-ẹlẹni lo nri tiwa.

Ọgbẹni Ẹrukobodo, ẹ ṣe pupọ, Ọlọrun ko jẹ ki a le parapọ ṣe nkan rere fun ilu wa.

Emi ni,
Ondo Sam. Adegbọla

### Ibadan Nikan Ko Lo Ni Iwo Orun

Ẹ jọwọ, Olotu, o dabi ẹnipe gbogbo ọrọ ti awọn ọkawe nyin nsọ nipa Ipinlẹ Yoruba, Ibadan nikan ni nwọn nda ori ọrọ wọn na si, sugbọn mo fẹ ki ẹ mọ kinni kan: Ilu Ibadan nikan kọ lo ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Abẹokuta wa nibẹ, Ọyọ wa nibẹ, Ọshun wa nibẹ, pẹlu awọn ara wa ni Ibinni ati Oke Odo.

Ti a ko ba fẹ da ija silẹ ki a mọ sọrọ Ipinlẹ Iwọ Orun bi ẹni wipe awọn ara Ibadan nikan ni nwọn ni.

Emi ni,
Akurẹ. J. Ọlajide.


Advt. NO. 134

### NOTICE

NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions :-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreign dignitaries ?

(ii) Do you consider that such awards should take form of :-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or
(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or
(c) both, or
(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-

The Secretary
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forwarded to the Secretary not later than the 30th of September, 1962

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ibadan Lo Mo

Boya enyin ọkawe mi ko niran ọrọ kan ti mo jisọ fun yin laipẹ yi lori ọrọ awọn oṣelu ọmọ Ibadan, mo ni ọrọ awọn ara mi, ọrọ Ibadan ni o mọ, o ko mo layipo ni ọrọ wọn. Ko ya mi lẹnu rara lati gbọ wipe ọrẹ Lọya (tabi Oloye ni ki npee?) Abdul Mọjidi Agbaje ti ra aṣọ kan ti nwọn ṣẹṣẹ nia ni Gbagi ni Ibadan ti nwọn npe ni "DẸHINKOROGUN" o si ti di dẹhin kọ ẹgbẹ Ọlọmọ-tuntun "Temidire" ti Oloye Akintọla ṣẹṣẹ fẹ da silẹ.

Ọrẹ mi, Mojeed ọmọ Salami Agbaje g o r i itẹ, kilode? Ṣe wa tilẹ duro na ki a da iwọ ọmọ-tuntun na. Nwọn ni ọmọ yio ku, ọmọ yio si ye ni, o yẹ ki a si ba ọlọmọ yọ.

Mo gbọ wipe ọmọ-tuntun na yio ye, nitoripe nwọn ti lọ gba Baba Abiye fun un ni agbegbe Ọshun, Iya Abiye si wa fun wa ni sẹgbẹdẹ ni Igbajọ leti Oshogbo

## O ko Mo Layipo

Ẹ tilẹ gbọ na! Mo gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) nmura lati se aṣeyẹ kan ti nwọn fẹ pe ni "Ẹ ku abọ" fun ẹ laipẹ yi; Dokita Opara, baba ẹgbẹ ọmọ Alakukọ ti o lọ si ilu Oyinbo ni nwọn nduro de. Ọtẹlẹmuyẹn ti o se ofofo fun mi ni, ti iwọ Lọya Agbaje ba gun ori ẹsin lati ọja Ayẹyẹ tan, awọn ẹmẹwa rẹ a tẹle ẹ, omiran ninu mọto ayọkẹlẹ ti a npe ni takisi ni Ibadan, awọn miran, ninu mọto Bọlekaja, awọn ogunlọgọ wọn a se lọrọ ẹsẹ-yaja-mọto lọ, sugbọn ara ni o nfi abọ si o, ẹ wa gba Ita Akere lọ.

Ti ko ba si ọrọ afiwepe nibẹ, emi paapa a wa sibi aṣeyẹ ọjọ na lati ba yin fenu kẹnu, nitoripe mo gbọ wipe malu meji wa nilẹ fun aṣeyẹ ọjọ na ati ọpọlọpọ agbe ẹmu lati Akanran, Odo Ọba, Arulogun ati Fiditi.

Boya ti mo ba mbọ sibi Aṣeyẹ na mo le ya ni ile ọrẹ mi Oloye Akinloye nitori mo fẹ fẹsẹ kan bọ sokoto ẹmu lọdọ rẹ; mo si le mu ọrẹ mi na lọwọ nitoripe nko tilẹ mọ inu ẹgbẹ oṣelu ti o wa nisisiyi; boya ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni, boya ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Temidire (Ọlọmọ-tuntun) ni, boya ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) ni tabi ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Afenifẹre (AG) ni o tun wa.

Ẹ jẹ ki a sọrọ na ko ye wa, ki a maṣe ni ọna ọfun, ẹna ọrun. Ṣe ki a ma purọ fun ara wa? Ibadan ni ọpọlọpọ yin mọ, ẹ ko mọ layipo.

## Ko Si Alabaro

Ko da mi loju w i p e Dokita Kwami Nkrumah, Alakoso Ijọba Ghana ni ilu awọn Aganyin ti o ni nwọn fẹ pa on tun ni awọn ọmọlẹhin Alabaro mọ nitoripe bi o ti nse ile aiye rẹ si ko ye mi mọ, mo si ti wipe ko ye on aiara paapa mọ.

Ṣe mo sọ fun yin wipe agbelebu olukuluku ọtọtọ ni ninu ose ti o kọja?

Agbelebu ti Jesu Krisiti lọjọ kinni lọhun ko le rara to ti Ọlọrun awọn Aganyin (Ghana), Dokita Nkrumah ti nwọn ni ko ni ku mọ.

Mọ gbọ wipe awọn Aganyin kan ni ilu Kumasi, awọn ti nwọn npe ni Ashanti, ologun ni nwọn jẹ, ti fi iwe ọjọ-iku sowọ si Dokita Nkrumah (Osagayfo) ni Christianborg pe awọn ni awọn yio paa.

## Agbelebu Igi Oro

Ṣe ẹ wa ranti ọrọ pataki ti mo sọ fun yin laipẹ yi wipe AGBELEBU OLUKULUKU ỌTỌTỌ NI? Awọn ti nwọn fẹ pa Jesu Krisiti ko sọ fun u ni ojukoju bayi wipe awọn fẹ pa a; awọn ti nwọn fẹ pa Anabi Mohamodu, nwọn ko sọ fun wipe ọna ti nwọn fẹ gba yọ si i niyi; awọn ti nwọn fẹ pa Ghandi awọn ko fi ọna na han awọn ara ilu India, [illegible] Oloye Ghandi se aiye ni rere (mo gbedi fun un ni [illegible]) awọn ọmọ araiye alije nle pa Orunmila (Agbọnniregun) kiri, nwọn ko sọ wipe ti o ba se itọrita [illegible] ki o duro de awọn.

Orunmila (Agbọnniregun) ni enikan ti o ba nwa iwakuwa a ri iakuri: Osagyfo (Dokita Nkrumah) ẹ jọwọ ẹ jẹ ki a sọra o, nitoripe aiye paapa ko si fun ẹnikan.

(Wo Irawo re Loju Ewe Keji)


### NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER

CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR

(a) "C" WAREHOUSE, APAPA QUAY

(b) "D" WAREHOUSE, APAPA QUAY

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate supervision for the handling of cargo at "C" and "D" Warehouses, Apapa Quay. The former warehouse is still under construction but should be completed before the end of this year.

2. Tenders which must be submitted on forms provided by the Authority for each warehouse separately and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL—TENDER FOR LABOUR "C" (or "D" as the case may be) WAREHOUSE" should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of MONDAY, 8th OCTOBER, 1962, NOT MONDAY, 17th SEPTEMBER, 1962, as shown in N.P.A. Notice No. 761.

3. Tenderers may tender for either one or both of the two warehouses.

4. Persons tendering for "C" Warehouse must use the Form of Tender bearing "C" Warehouse and persons tendering for "D" Warehouse must use the Form of Tender bearing "D" Warehouse.

5. The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10 for each warehouse, payable to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quay. The deposit will be returned on receipt of a bona fide tender.

6. Only applications from labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

7. Applicants wishing to view either "C" or "D" Warehouse or both before submitting tenders should apply in person to Chief Traffic and Commercial Manager, Apapa Quay.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N. P.A.Notice No. 764.
10th September, 1962.

## Awon Imale Ni Ki Ijoba Ra Ile Si Meka

(O bere loju ewe keta)

Nigeria ti awon yio ko ago gbigbe si fun awon omo Nigeria ti o ba wa si ilu na

Onirohin wa ni on gbo wipe laipe yi ni Alhaji Nuhu Bamali, Minisita alamojuto awon ero Meka, fi iwe irohin kan sowo si Alhaji Tafawa Balewa, Alamojuto Ijoba Apapose, wipe asiko to fun Ijoba lati gba ile lowo Ijoba ilu Meka lati ko ago gbigbe si fun anfani awon ara ilu Nigeria ti nwon yio ri asia Ijoba si, ki ogunlogo omo Nigeria le mo tele ri ara won, ki nwon ye sonu silu onilu.

Akowe egbe Imale na, Alhaji Y. K. Yakubu ni ti nwon ba le ba awon gba ile na si Meka inu awon yio dun, wahala awon ododun a si din ku.

Nwon ti fi iwe-ebe won ranse si Ijoba lori oro na.

---

**E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ti O Kun Fun Irohin Aladun, Ki E Si Ma Polowo Oja Nyin Si Inu Re Losose.**




The load is heavy, the ground difficult, the engine is working at full power and yet the driver has perfect control. The light Mercedes-Benz recirculating ball steering is precise to a fraction of an inch. Exact manoeuvering, safe use of marginal space, absolute track steadiness and excellent lock are features of this steering which is just one of the many advantages that all Mercedes-Benz trucks and buses have in common.

**Precision to a fraction of an inch**



MERCEDES-BENZ

Available at:

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (EB) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA

Sub-Distributors:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.

# Nigeria Takes Up Cable And Wireless

LONDON–Another partnership venture between Nigeria and Britain was launched in London, yesterday, when an agreement was signed by the Nigerian Federal Minister of Communications, Mr. Olu. Akinfosile and Sir John Macpherson, chairman of Cable and Wireless Ltd, and a former Governor of Nigeria. "An example of practical co-operation in the modern and developing Commonwealth," was how they described it.

Also present at the signing ceremony were Mr. T. O. S. Benson, Nigerian Minister of Information, and Mr. E. G. Lewis, Permanent Secretary to the Ministry of Communications.

The agreement was for a new company to be formed in Nigeria, with a Nigerian majority on the Board, to take over the local assets and services of Gable and Wireless Ltd. in Nigeria.

The new company, to be called Nigerian External Telecommunications Ltd., will be invested by next January with an authorised capital of about £2 million, financed jointly by the Federal Government and Cable and Wireless, in a proportion of 51o/o to 49o/o. The initial term of parthership will be for five years.

The long-term objective was on all-Nigerian executive staff and to this end Cable and Wireless has undertaken to continue to train Nigerian staff at all levels and in all aspects of the new company's work, said Mr. Akinfosile.

Already a total of 19 Nigerians were at varying stages of training as engineers.

Sir John Macpherson said this agreement showed the way of the modern Commonwealth and it was entirely right that Nigeria should have the major share in the new development.

The history of Cable and Wireless in Lagos dates back to 1886, when the first submarine cable was landed on Victoria Beach for the African Direct Cable Company.

**Read**

**And Advertise**

**In**

**Eleti–Ofe**

# U. S. Justice Department Investigates Negro Church Bombings

WASHINGTON–The U.S. Justice Department report on the bombing and burning of Negro churches in Southwest Georgia has been turned over to President Kennedy for study, according to Pierre Salinger, the President's Press Secretary.

The President received the report when he returned to Washington on Monday after a weekend in Newport, Rhode Island. He discussed the church bombings and burnings with his brother, Attorney General Report Kennedy, before returning to Washington.

The Federal Bureau of Investigation, a division of the Justice Department, and local authorities began inquiries to determine whether the buildings has been burned in an attempt to intimidate prospective voter registrants.

One Negro Church was destroyed in Leesburg, Georgia, and another in Sasser, Georgia, in a series of incidents apparently connected with a Negro vote registration campaign. Both churches had been used for voter registration meetings.

The campaign is being conducted by the student nonviolent coordinating committee which consists of white and Negro students and young adults from the northern and southern parts of the United States.

If the investigation produces evidence that the hurch bombings and burnings are linked with the vote registration campaign, the U. S. government will probably intervene on the Negroes' behalf under the civil rights act of 1960.

On previous occasions, both the President and the Attorney General have indicated that the Federal Government would not tolerate interference with citizens' right to vote.

**Read**

**ELETI–OFE**

**Every Week, Because Eleti-Ofe is The Leading Bilingual Weekly Newspaper In Nigeria.**

# Eleti-Ofe D'araba

IBI IJOKO AWAMOTO INU AUSTIN S 200

DARA TOBẸ TO FI NMU ARẸ AWAMỌTO

DINKU PUPỌPUPỌ –

O NMU MỌTO—WIWA RỌRUN PẸLU AISI EWU!



Mọto Austin to lagbara yi tunbọ nṣe alekun wiwa-mọto laisi ewu nitoripe a ti ṣe e dara tobẹ, eyiti yio jẹki iṣẹ rẹ jafafa siwaju si i, ki ere si ma wọle pupọ fun ọ. Mọto S ati 1 200 ni inu fifẹ, to si balẹ fun eru kiko; jigi iwaju rẹ lagbara, o si njẹki enia riran dada; ojuferese rẹ njẹki mọto se wa ẹhinrin laisi ewu. Bere pe ki a wa a wo ki o ri i.

Nigeria Head Office 237 — 241 Igbosere Road, Private Mail Bag 2083, Lagos. Garages at Aba, Agege, Benin, Ibadan, Jos, Kano, Lagos, Onitsha and Port Harcourt.

AUSTIN

S 200

(S 200 1½ ton; 1 200 – ...)

SCOA Motors

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU): OLA. ONATADE
15, Kosoko St., Lagos.

## Awọn Oloye Lọ Tuba Fun Ọba Adele

Awọn Oloye mẹrun ninu awọn Oloye Eko ti Ọba Adeniji Adele Keji rọ loye laipẹ yi, awọn Oloye Asọnjọn Ereko, Onilegbalẹ, Ọbanikoro, Olumẹgbọn ati Olorogun ti lọ tuba fun Ọba na ninu ile rẹ lana; nwọn ni awọn ko ni ṣe bẹ mọ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, awọn Oloye na ti kọ iwe-ẹbẹ si Minisita Akamojuto ọrọ Eko wipe ki o gba awọn ati pe awọn ko ni ba wọn da si ọrọ ilu mọ. Awọn ko si ni faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan mọ.

Ọba Adele na ko ti fesi fun wọn.

## Gbadamosi Pe Omo Ajao Lejo

Alhaji S. O. Gbadamọsi, alakoso ile iṣẹ ti nwọn nṣe awo ni Ikorodu pe ọmọ Ologbe J. A. Ajao ti nwọn npe ni Aderọgba Ajao lẹjọ si Kotu garan fun ebu ti o ni ọmọ na bu on.

Ninu iwe ipẹjọ na, Alhaji Gbadamọsi ni ki Ijọba ki o ba on gba ẹgba medọgbọn pọnun (£50,000) lọwọ ọmọ na fun orukọ on ti o bajẹ, ti o nsọ kakiri wipe gbese ti on jẹ baba rẹ ti o ku laipẹ yi, on Alhaji Gbadamọsi ko san owo na rara.

Alhaji Gbadamọsi ni bẹ on ko jẹ baba ọmọ na ni epinni nigba aiyẹ rẹ.

## E ka

### Itan Oba Alake

### Loju Ewe Keta